# ORÍ ÒKÈ INÁ ÀTI IṢẸ́ ÌYANU

Olú Ilé Iṣẹ́ Ìránṣẹ́, Ìpínlẹ̀ Èkó, Nàíjíríà.

**Oṣù Kárùn, Ọdún 2025**

**Agbára Gbọ́dọ̀ Pàrọ̀ Ọwọ́**

## OṢÙ KÁRÙN, ỌDÚN 2025

**1. Ẹ̀nyin olùkórè nín’oko!**
T’árẹ̀ fẹ́rẹ̀ mú tán;
Ẹ rọ́jú dúró de Olúwa,
Y’Ó s’agbára dọ̀tun.

Àwọn tó dúró d’Olúwa
Y’ó s’agbára wọn d’ọ̀tun,
Nwọn ó fi ìyẹ́ fò,
Nwọn ó fi ìyẹ́ fò bí ìdì,
Nwọn ó sáré, nwọn kì y’ó k’árẹ̀;
Nwọn ó rìn, kì ó rẹ̀ wọ́n;
Nwọn ó sáré, nwọn kì y’ó k’árẹ̀;
Nwọn ó rìn, kì ó rẹ̀ wọ́n;
Nwọn ó sáré, nwọn kì y’ó k’árẹ̀,
Nwọn ó rìn, kì ó rẹ̀ wọ́n.

2. Nígbà àrẹ́ àt’irẹ̀wẹ̀sí,
À ngb’ọkàn wa sí Ọ;
Lẹ́yìn t’agba Olùgbàlá gbọ́,
Kí l’a ó tún bẹ̀rù?

3. Ẹ yọ̀! Ó mbá wa gbé lọ́jọọ́,
Àní títí d’ópin!
Wòkè! ẹ sì ma tẹ̀sìwájú
Y’ó fùn nyín l’ágbára!

1. **Ẹ dide, ọmọ ìgbàlà**

Ẹ̀yin t'ẹ fẹ́ Olúwa;
Dìde, ìlú alágbára
Kí ọ̀tá tó dé Síòn.

F'agbára rẹ kọrin kíkan,
Bí ìró omi òkun;
Nípa ẹ̀jẹ̀ Krístì Jésù
Àwa ju aṣẹ́gun lọ,
Àwa ju aṣẹ́gun lọ,
Àwa ju aṣẹ́gun lọ;
Nípa ẹ̀jẹ̀ Krístì Jésù
Àwa ju aṣẹ́gun lọ.

2. Ẹgbẹ́ mímọ́ ti ìgbanì

Tí wọ́n ti nrin ọ̀nà yí;
W'àsíá wọn t'ó nfẹ́ lẹ́lẹ̀
A ṣẹ́gun nípa Krístì.

3. A ti gbé 'kú mì ní 'ṣẹ́gun,

Ìyè wa mbẹ n'nú Krístì;
L'ọ́jọ́ 'farahàn Olúwa
A ó hó ìhó ayọ́.

4. Láìpẹ́ aó dé'bi ìtẹ́ Rẹ̀,

A ó sì mọ Ọba Ògo,
Níbẹ̀ aó kè, Kábíyèsí"
Gbogbo wa y'ó gba èrè.

## ỌRỌ̀ AGBÁRA

1. Nípa agbára tó mbẹ nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù, ayọ̀ àwọn aninilára lórí ayé mi yóò di ibànújẹ́ lónìí, ní orúkọ Jésù.
2. Ìkórajọpọ̀ àwọn agbára ìkà tó lòdì sí itẹ̀síwájú mi yóò wólulẹ̀ lónìí, ní orúkọ Jésù.
3. Nípa agbára tó mbẹ nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù, gbogbo agbára òkùnkùn tí wọ́n yàn láti dènà ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ ìfarahàn ògo ayànmọ́ mi yóò kú lónìí, ní orúkọ Jésù.
4. Gbogbo agbára òkùnkùn tí wọ́n yàn láti mú ìlọ́ra bá itẹ̀síwájú mi, gbọ́ ọ̀rọ̀ Olúwa, òní lòpin rẹ, kú báyìí, ní orúkọ Jésù.
5. Gbogbo ìpinnu búburú fún ayànmọ́ mi yóò kú nípa iná lónìí, ní orúkọ Jésù.
6. Gbogbo agbára òkùnkùn tí sàtánì yàn láti jẹ́ kí n dìde, kí n tún ṣubú, òní lòpin rẹ, kú, ní orúkọ Jésù.
7. Gbogbo agbára òkùnkùn ilé bàbá mi, tí wọ́n yàn láti dá alàjá ètò-ìṣúná mi dúró, kú báyìí, ní orúkọ Jésù.

## ÀDÓ ỌRỌ̀ NÁÀ

**Isàíàh 40:29:** Ó nfi agbára fún alárẹ̀; Ó sì fi agbára kún àwọn tí kò ní ipá.

**Fílíppì 4:19:** Ṣùgbọ́n Ọlọ́run mi yóò pèsè ní kíkún fún gbogbo aìní nyín, gẹ́gẹ́ bí ọrọ̀ Rẹ̀ nínú ògo nínú Krístì Jésù.

**Orin Dáfídì 107:20:** Ó rán ọ̀rọ̀ Rẹ̀, Ó sì mú wọn lára dá, Ó sì gbà wọ́n kúrò nínú ìparun wọn.

**Orin Dáfídì 147:3:** Ó mú àwọn onírora àyà lára dá: ó di ọ̀gbẹ́ wọn.
**Isàíàh 57:18-19:** Mo ti rí ọ̀nà rẹ, èmi ó sì mú u lí ara dá: èmi ó sì tọ́ ọ pẹ̀lú, èmi ó sì mú itùnú padà fún u wá, àti fún àwọn aṣọ̀fọ̀ rẹ̀. Èmi li ó dá èṣo ètè; Alàfíà, alàfíà fún ẹnití ó jìnà réré, àti fún ẹnití ó wà nítòsí, ni Olúwa wí; èmi ó sì mú u lí ara dá.

**Rómù 8:37** Ṣùgbọ́n nínú gbogbo nkan wọ̀nyí, àwa ju ẹnití ó ṣẹ́gun lọ nípa ẹnití ó fẹ́ wa.

**Máttéù 9:21** Nítorí ó wí nínú ara rẹ̀ pé, Bí mo bá sà lè fi ọwọ́ kan aṣọ rẹ, ara mi ó dà.

**Deutérónómì 7:15:** OLÚWA yóò sì gba àrùn gbogbo kúrò lọ́dọ̀ rẹ. Kì yóò sì fi ọ̀kan nínú àrùn búburú Égíptì, tí ìwọ mọ̀, sí ọ lára, ṣùgbọ́n òn o fí wọ́n lé ara gbogbo àwọn tí ó kórira rẹ.

**Isàíàh 58:8:** Nígbànà ni ìmọ́lẹ̀ rẹ yóò bẹ́ jáde bí òwúrọ̀, ìlera rẹ yóò sọ jáde kánkán: òdodo rẹ yóò sì lọ ṣájú rẹ; ògo Olúwa yóò kó ọ jọ.

**Jeremíàh 17:14:** Wò mí sàn, Olúwa, èmi ó sì sàn; gbà mí là, èmi ó sì là; nítorí Ìwọ ni ìyìn mi.

## <u>ÀDÚRÀ ÀDÁGBÀ</u>

**<u>ÌJẸ́WỌ́: ORIN DÁFÍDÌ 91</u>**

1. Ọlọ́run, dìde, kí O sì fàtu ohunkóhun tí O kò gbìn sínú Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
2. Ọlọ́run, jẹ́ kí iná ìsọjí bà lé Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
3. Bàbá, jẹ́ kí àánú ká kúrò lọ́dọ̀ gbogbo ọ̀tá ayé mi, ní orúkọ Jésù.
4. Bàbá mi, jẹ́ kí ohun gbogbo tó ti ṣiṣẹ́ fún àwọn ọ̀tá mi rí bẹ̀rẹ̀ siní ṣiṣẹ́ fún ìparun wọn, ní orúkọ Jésù.
5. Gbogbo ọ̀tá ilé bàbá mi tí ó kọ̀ láti ronúpìwàdà, kí òòrùn pa yín ní ìgbà ọ̀sán àti oṣùpá ní ìgbà oòru, ní orúkọ Jésù.
6. Títí láí ní èmi yóò ma gbé nínú ihò ọwọ́ Ọlọ́run, ní orúkọ Jésù.
7. Ìṣe àjẹ́ ìyówù lábẹ́ omikómi, tí wọ́n yàn lòdì sí ayé mi, gba ìdájọ́ iná, ní orúkọ Jésù.